**Ikede**

Ase Ikede yi fun gbogbo Inyin Okewe wa ati asoju wa wipe, eni kéni ti owo ba seku si owo re ki o tete fi ranse ni-kori gbogbo obun elo ti o fi gbewe irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse so da Iwe re duro so si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI'L'EJO

**ELETI - OFE**

Gbarada, ti eleggan l'oku Irohin aladun pelu oro ibalaiye ni o mbe ninu Iwe Irohin Eleti - Qfe.

E ma ka lososе.

VOL VII No 433 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA SEPTEMBER 17 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2)

# Otunba Ti Ikija



**Omo'ba Regina O. Fowora**

Aworan inu iwe wa yi niti agunleyinju om'oba Regina. O. Fowora ninu aso oye re lekun rere ni asiko ti nwon fi je oye Otunba ti Ikija nilu Ijebu - Ode.

Lojo ifijoye re, iroh n ko to afojuba ni ojo na je, nigbati gbogbo ilu ndun yungba fun tokunrin-t'obinrin, ohun jije te enikeni l'orun, bena si ni ohun mimu, ko si Oti ti ko peju nibe, amuti ati ajeti ni fun enikeni, ayafi eniti ko ba de ibi aseye ifijoye na.

Otunba Ikija ti ilu Ijebu-Ode, Aromamo, Obinrin.

OYE AMORI O.

## Odaran Gbadura Fun Adajo

Awon Ogbole okunrin Gambari marun ti awon Qlopa mu fun esun ole afole ti nwon si nko ohun jamba bi Oko, ada ati awon nkan bawonni kiri ni Adajo ju won s'ewon fun bi odun meji ti o fi de osu mefa.

Awon elegiri na bu s'erin nigbati nwon nda won jade lati inu Apoti-eri, nwon si gbadura fun Adajo ni ede Hausa.

## IYAWO DUN LOSIGIN

Ko si bo ti ri ni igbeyawo alarinrin merin, eyiti Ogbeni Lawani Emi-Abata ti o nse Asoju fun Iwe Irohin Eleti-Ofe nilu Atan Qtta gbe fun awon omo re, o fi meji fun oko lojo kanna.

Igbeyawo na minringindin, awon enia dabi omi ni Opopo Banjoko St. awon ara, ati ebi, gbogbo lo peju pese.

Lehin ti nwon gbe yigi lo, ti nwon si gba yigi tan, ti awon Alufa jeun ti nwon gba owo ati Obi, nigbana ni faaji sese wa bere. Awon enia to wa sibe fere le ni irinwo enia.

Awon oko iyawo ni, A K. Lawal, M.L. Emi-Abata, enikokan gbe iyawo meji-meji Oruko awon omobinrin ti nwon sin fun oko ni Iyanatu Abeke ati Afusatu Akanke.

Die ninu awon egbe ati gbajumo ti o wa sibi iyawo na ni Egbe Ifelodun, Oredegbe, W.K. Okoya Ahadji Balogun, Shelle Balogun, A Bada, Ahaji Nua, Nosiru, ati Sulu Balogun, Raimi Baba Muli, T. Ovegbola, S. Gbolade Mohamed Balogun. Rabiyu, Amida, Liadi, Y.K. Oladehinde Wahabi Adesina, S. Balogun, Rasaki, Tiamiyu Elegbaa-Ada ati Ademiju Eleti Ofe.

Gbogbo won lo se inawo repete awon obinrin Eko fi aso dara lojo na, wa wo idi nlanla ati idi rabata.

## Iwadi Igbimo Ibadan

Qpolopo ninu awon to wa jeri ni nwon wipe awon fun Qgbeni Adelabu l'owo bi ponwun mewa, medogun, ati ogun ponwun tabi jube-lo. Lati igbati oluwadi ti bere ise na. alaye bi awon eleri to yoju wa lati jeri ti se fun Qgbeni Adelabu l'owo ehin ni nwon to fi ori iyen ti wipe awon yio tun bere si se afihan miran nipa ona eru ti nwon fi nfun awon alagbase nise ati ona ti nwon ngba gba owo-ode, (Tax Collection)

Nigbati nwon tun pade lori iwadi yi ni Qgbeni E.W. J. Nicholson ti ise Oluwadi ise Igbimo Ibadan so wipe lori gbogbo ejo ti awon eleri ro eyiti on ko ri eri to lori re ko ni si ejo riro fun awon ti oro na kan sugbon awon eri ti nwon yio je riro niti Qgbeni S, A Akinyemi, ejo ti Igbon, ti Ibudo moto ni ogunpa, ati James Adegun ati Adeleke Ogunsola,

Oluwadi si so wipe lori gbogbo awon eleri ti on so wipe ko ni si riro fun awon ti oro na kan, ni on ni eto lati soro lori nwon nigbati on ba ma fi abo iwadi ti on se fun Ijoba Iwo-orun

Bi oro iwadi na ba ti nlo si ni ao ma fi eyiti o ba je pataki to yin leti ninu Iwe wa,

## Egbaa Enia Yio D'asunta L'Abule Ije

Abule ti a npe ni Ije l'eba Qbalende, ni a gbo wipe Ijoba fe gba lati tunse fi kun Adugbo ti a npe ni Oke Suna ki o le fe sii.

Eyi yio so awon enia bi egbaa di alaini ile lori A si gbo wipe Olaye Onilegbale ti fi iwe si de wipe ile Ile ti ile Oye Onilegbale ni ise lati igba Isandaly. Iwe Kobo nita Tinubu ni oro na.

Oro po mbe!

## A Dupe, A Tun Ope Da

Omo'be Regina O. Fowora, Oloye Otunba Shewaolu ti Ikija, Ijebu - Ode, fi eyi dupe gidigidi lowo awon ebi, ore ati ojulumo re, to wa ba s'eye ati awon to ranse ayo si i, ni asiko ti a fi j'oye Otunba ti Ikija, Ijebu - Ode.


## Chairs For Rent

APPLY

OFE

NO. 3, AIBU STREET LAGOS.



Only Shell's patented I.C.A. gives you ALL the power of the NEW higher octane motor spirit

The most powerful motor spirit you can buy

SHELL

WITH

I.C.A.

IGNITION CONTROL ADDITIVE

Fill up and FEEL THE DIFFERENC


## Iwuye Olofin Iseri Pa Bambari

Ni ojo ose tokoja ni nwon se iwuye Oba Samuel Ayodele-Keji, ti ise Oba Olofin ti ilu Iseri Ogbeni Kusimo ti ise Oloye Oluwo ti ilu Iseri ni o se eto iwuye na, awon Oloye Asajon ati Osunba Iseri l'o se isongbe re.

Oloye Oganla ti Iseri Ogbeni G. Akinola, Taiwo ni o se Oga eleto ojo na, o si se eto na daradara titi ti gbogbo re fi de ipari pelu igbadun, Oloye Ayo Ajala, Bajito, ilu Iseri, akuro-yejo okunrin ni o ka iwe itan bi o ti se je wipe Ogbeni Samuel Ayodele-keji ni eniti ipo ola na tosi.

Ki a daruko die ninu awon gbajumo enia to peju-pese sibi aseye iwuye na- awon enibi:- Ogbeni Mosalewa Thomas, S.B. Folami, Abake Fasina, Esu Jakande, Modupe Taiwo, Morinola Taiwo, Saka Ayodele ati opolopo enia ti aye ko gba lati daruko tan.

Oye amori o.

## Oba Ati Ojoye Ijebu-jesha Se Nri Ise Egbe Alakuko

Ninu ipade kan ti nwon se ni Ijebu-Jesha, nwon ke si awon Olugbimo Ibile wipe ki nwon o lo yi iwa padu si rere.

Ese awon Olugbimo Ibile ati Alaga won fere pe sibi ipade na tan. Nwon ka ese iwa abuku si awon Oloye ati aibikita fun ofin ati asa Isedale si won lorun. Awon enia to wa si ipade na le ni edegbeta.

Ijebu-jesha ni ilu Ogbeni C.O. Komolafe ti ise okan ninu awon to wa ninu Igbimo apapo nla.

Nipa ise won ni enyin o fi mo won.

## Awon Onijibiti Se Nkari Aiye

ABA— Laipe u a tun gbo irohin kan pe awon onijibiti ti tun de ilu kan ti a npe ni Aba, nwon se titi to be ge ti nwon fi fi omodekunrin kan se jibiti n itorisiga (cigarette)

A gbo pe ni ilu Aba awon obi omodekunrin kan ran omo won ni oja pe ki o lo ra ohun jije, omo yi si lo gegebi awon obi re ti wi fun u. Nigbati omode yi de oja, beni o pade okunrin onyibiti yi, okunrin yi si fi ogbon ewe tan omode yi pe ki o ba on de ibiti on yio gbe ra siga.

Nigbati nwon de odo onisiga lati ra siga, onijibiti yi wo gbogbo apo re ko ri owo, o si so fun onisiga pe on gbagbe owo on si ibiti on ti koko gbe ra nkan, beni okunrin yi ba lo, o si fi omode kekere yi sile.

Alo lari a ko ri abo onijibiti yi mo, onisiga wa bere lowo omokekere yi pe bawo ni o ti je si onijibiti yi, omo na si so pe on ko mo ri rara. lesekese ni onisiga yi ti lo so fun awon olopa ilu yi nwon si nwa okunrin yi kiri di bi a ti nso yi, omokekere yi si pada lo si odo awon obi re.


### AFUN NI L'OKUN ARA

Bi iwo ba ru (THIN) o le san'ra ki o si l'okun lara to bi iwon okuta mewa de Ogbon tabi jubelo.

A ti se awari ona eyi, kowe si wa, ki o si fi Sile meji (2/-) sinu iwe re lati so ara to fayi di olokun-ara.

ADRESS:- ACTIVITIES, KINGSWAY, (T140) DELHI- 9, INDIA.



NOW,

AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY
20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN



### ASO ENIA KUKURU DI GUNGUN

Bi iwo ba ufe ki o gun die si (Increase Height) kowe fun "ILANA TO DAJU" lodo wa. O dara fun Okunrin ati Obinrin.

Fi Ogbon Sile (30/-) sinu iwe re, ibase Postal Order, Bank Draft, tabi SEKI Arinrin-Ajo ti Gesi tabi America. Ao Gba.

ADDRRESS:-
ACTIVITIES (D 240)
KINGSWAY, DELHI-9, INDIA.

# Koseku Ko Se Eiye Ajawo

Lati Qwo Eso Ikoyi

Kini a npe ni Ajawo ?. Ajawo je iru eranko kan ti o fi ara jo Ekute, o si tun ni iye ti o fi nfo gegebi ti eiye. Alaiikua Ekute ko nfo beni ko si eiye ti o lehin. Irufe eranko yi ni a npe ni Ajawo, ti o da ija sile larin Eranko ati Eiye.

Nigba gbogbo ti awon eiye ba soro asiri, ni awo oro yi ma nya s'arin awon eranko, nwon yan Alapandede lati fimu-finle wadi oro na, nigbati o se, laifa oro gun, Eiye Owiwi ridi oro na, o si mu wa si awujo awon eiye. O wipe mojuba Ogongo baba eiye, mo si tun juba Akalamagbo ati enyin eiye were-were. Afefe ti fe, a si ti ridi adie, toto, o se bi owe.

Lale ana, mo lo lati lo se alami gege bi awon Eranko ti se ngbo awon oro asiri ti a bo so, mo si ri Ajawo, ti o bo sode ti o si bere si tu gbogbo asiri wa sile niwaju awon eranko. Inu bi gbogbo awon eiye si Ajawo nigbati nwon gbo oro yi, nwon wa reke sile de Ajawo,

Dide ti o de, gbogbo awon eiye ko, nwon fi ti, nwon lu u, gbogbo ehin re wo danu, o wa ku ehin okokan meji nse ni o wo titi dele. Nigbati awon eranko gbo nipa oro yi, inu bi won, gbogbo won si pinnu wipe, ibagbe awon pelu eiye ko ni le wo lori ile aiye nipa bayi nwon gbogun si awon Eiye.

Ogongo lo se Balogun fun awon Eiye, Erin Ajanaku, lo se balogun fun awon Eranko lo soju ogun. Ija na po to be ge, nigbati Erin ati Ogongo pade loju ogun yi, ni wara sesa Ogongo ti yo oju Erin mejej je, sugbon Erin ko jeki Ogongo lo, o fi owo ija re ro mo o lorun, O bere si gbe Ogongo sanle titi omo ika ese re fi ya ku meji. O si se li Opin ija yi, orun Eiye Ogongo gun s waju, gbogbo iye alarabara ara re lo tu danu tan.

Lati ojo na wa ni Ogongo ko ti laso lara mo ti o di olorun gigun, sugbon Erin ko loju, gbogbo omo ika re lo ti se danu, Bakanna ni awon eranko ati eiye yoku fi ara gbogbe. Gbogbo ara Ekun ni Eiye Idi ko nla.

Lai'a oro gun, nigbati ija na po, ni Obatala da si fun won o pari ija na, sugbon totun tosi won ko fe gba, awon eranko so wipe Balogun won ko loju mo, ayafi bi awon ba pa Ogongo, awon Eiye si tun wipe, awon ko ni gba nitoripe Balogun won ti di Alakisa ati Qlorun-gigun.

Qbatala lo sile oju ko si oju nlanla gegebi ti esin mo ayafi kekeke gegebi ti Adie, lo ba fun Erin ni eyini. O si tun lo sile aso, akisa li o ku, lo ba mu fun Ogongo sibe-sibe eyi ko te won lorun

Nigbana ni Qbatala wa lo agbara re lori won nitori ki aiye le simi, o pase wipe ki awon Eranko ma gbe orile, ki nwon si ma fi igbe se ile. Sugbon ki enikeni mase ba Ajawo rinpo mo.

Awon Adie, Pepeiye, Awo, Tolotolo so wipe awon ko le fi ore won ti o je eranko sile nitorina awon yio ma ba won gbe po. Bakanna ni awon Qwawa, Qbo, Lagido, Aaya,, Ijimere so wipe, awon ko le ya pelu awon eiye, awon mba won lo. Qbatala si gba fun won,

Lati ojo na wa titi di oni, Ajawo ko gbodo jade osan ayafi loru. Ko seku, ko s'eiye A-ja-wo!


# AWO IKQRIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

## Lo ra won ni sobu S. C. O. A.

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon eru ti o se pataki ranse.

## S. C. O. A.

Head Office:- 40, Marina, Lagos.

Show Room: Martins/Broad Street, Lagos

ATI NI

Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.

# ELETI QFE

A-NIJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28 Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI-QFE LAGOS"
Phone 23370

VOL VII NO. 433. LAGOS SATURDAY SEP. 17 1955.

## Tembelekun

Kini itumo Tembelekun ? Tembelekun je iwa buburu, iwa innibini, iwa alferan eni ati iwa ikorira enia. Iwa yi je iwa taruku ti ko dara rara, iwa na si sopo l'arin awa omo Yoruba, irufe iwa Tembelekun yi ki itun nkan se rara ju ki o ba nkan je lo.

On ruru iwa Tembelekun ni o wa. awon elomiran ylo ma binu omo eni eji won leri asan beni awon elomiran ewe, a si ma se ojukokoro si omo enikeji won, awon enia ti ko gba Olorun gbo ni o po ninu awon oniwa buburu yi.

Bi Olorun Oba ba da aburo ju o lo gba wipe ise Olorun ni, bi omo re ba nga, jeki inu re dun si, bi aladugbo re ba nse ohun rere, jeki o dun mo o ninu, ki o si ranti wipe bi o fe, bi o ko fe, Oluwa Olorun ti se ise re pari.

Ninu gbogbo ayekaye ti enia ba wa l'ode aiye yi, ki o gba wipe Olorun l'o fi on si aye be, mase binu omo enikeji re, bi iwo ba ti nro rere si ara re beni ki o si ma ro rere si eda egbe re.

Iwa Tembelekun ko dara, iwo mase di'te si eda elegbe re.

Iwa ti Olodumare ko fe ni iwa Tembelekun.

## Akiyesi Pataki

Nipa iwe ti a ri gba lati owo enyin Qkawe wa, a fe fi eyi so fun yin wipe iwe irohin wa Eleti-Qfe, Elede meji ni (Bilingual Newspaper) Ede Oyinbo ati Ede Yoruba, ni a fi Rejista lodo Ijoba. Nitorina, a ko le se ki Ede Oyinbo ma si ninu re, sugbon a ko ni je ki o po to Yoruba.

Bi o ti je niyen o.

OLOTU

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ebin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## Ekute Ile Paramo.



OLOLA S. L. EDU

Ologinni t'ajo bo, aworan iwe wa yi niti Olola S. L. Edu ti ise okan pataki ninu awon olugbimo Ibile ti ilu Epe, on ni ise Akonije Ijo Faramora ti Alaiyeluwa Olu Epe je Baba - egbe fun Ijo Faramora ti ilu Epe na.

Ni ojo Monday otunla ti ise ojo kokandinlogun osu yi ni awon yio si ile Igbimo tuntun na fun akoko pade awon eni - o'a ti nwon yan si'nu Ajo Igbimo Ibile ti Ilu Epe.

Bi o ro ba dun, enyin okawe wa, orin ni a fi nko :-
Olola Edu pagbo sebe,
Oyinmomo,
Olu Epe gba k'otowo
Oyinmomo,
Ki Edumare se imoran yin ni rere, ni adura tiwa.

## Amotekun Pa Aburo Egbon M'ori Bo

KALABA — Ni agbegbe ilu Kalaba ni irohin yi ti kan wa pe Amotekun pa aburo o fi egbon re sile,

Awon odomobinrin meji tegbon taburo jijo lo si Oko lati lo mu su wa fun awon obi won, sugbon nib'ti awon Qdomobinrin yi gbe nsise,, won ko mo rara titi ile fi su nigbati awon omo na npada bo wa si ile ni won ba pade ogbologbo Amotekun kan lona

Awon mejeji sa asala fun emi won sugbon owo Amotekun te aburo; o fa a ya perepere.

Egbon ni o m'ori bo ti owo eranko buburu na ko te. Lowo ewu osan ati toru, Oluwa rere gba wa.

## Ari Nkan Ile Di Ole

Qkunrin kan ti o so wipe on ri Fila Idara ati Aburada kan be nibi Ile Iworan ale (Cinema) l'Eko ni adajo Kotu Yaba ni ki o lo san ponwun meji abo (£2. 10 0) tabi ewon osu kan,

Adajo so wipe o to asiko ti enia ni lati mo wipe ohun olohun ti enia bari be ni koro kan loju titi ko ni ebun Qlorun, Etoti eniti o ba ri nkan he be ni lati se ni kio lo fi han awon olopa,

Enyin okawe wa, o ye ki a se akiyesi irohin yi, ki enikan si fi ko ogbon.

## Eyi Ni Itumo Awon Ede To Jade Ninu Iwe Wa L'ose Keta.

1. Ogbeni ti a npe ni Kadara je eniti o feran lati ma soro ti ko ni dara lori ohun ti Olorun yan fun enia lati ma se lode aiye. Ogbeni Kadara ko si mo wipe iwa ko ni dara ti on paapa nhu je apakan ayanmo ti a da mo on.

2. Moremi Ogun lo gba ogun tire nigba okowo lodo Asoju, bi ko ba si ti awon agbagba okowo enia ti o dide si oro na ni, iba da rogbodiyan sile, ninu eyiti won iba fi egbogi se ara won lese. Nigbehin oro yi, nwon ni lati se etutu si orisa Ogun.

3. Owo ni gbongbo ese, sugbon Ogbeni ti a npe ni Owo ko nani ese yi, bi ko ba si ti arun Owo ti o nyo o lenu ni oju ibiti eran gbe fi Owo ori re kan a ; Bi o si ti wu ki enia mo owo ni sise to, ko le se ki o ma d'ese owo.

Eso Ikoyi.

E ma ka iwe irohin ELETI - QFE

## Ifijoye Olori Omo Ilorin

**Eko** Irohin ko to afojuba ninu Iga Idunganran l'Eko, nibi ipade kan ti Alaiyeluwa Adeniji Adele Oba Eko fi ase si wipe awon Ọgbeni Alabi Baba ati Bello Iyanda lo ye fun oye Olori Ọmo Ilorin ni Eko ati ni Apapa.

Alaiyeluwa Ọba Eko se adura lopolopo fun awon Oloye mejeji, gbogbo ese awon Oloye Onifila funfun lo pe sibi ifijoye yi.

Die ti a ye wa fun wa lati daruko ninu awon alabaseye yi ni Salawu Balogun, Are Sanni, Jonmo Ọmo Ilorin, Baba Tuwo, Alufa Mustapha, Buraimoh Dogo, Alabi Balogun Alabi Megida ati awon bebe

## Igbeyawo Miringindin

Ni ojo ose ti ise ojo kokanla osu yi ni a se igbeyawo omidan Modupe Cole, omo Ọgbeni E. A. Cole ti opopo ona Agege ni Idioro ati ogbeni S. E. Ọla ti ile-ise U. A. C. l'Eko,

A se igbeyawo nile baba iyawo ni Idioro l'opopo o u a Agege. Ase repete ni Ọgbeni Ọla ati iyawo re se fun awon ebi, ore ati ojulumo re ni ile won, 63, Queen Street, Yaba,

Nibi ariya igbeyawo na, Ẹro akorin olohunyo tubo nu ere ya lojo na, ti awon olubaseye ngbadun yungba, Awon to wa sibi iyawo na ni Ọgbeni H. O. Omoge, moba Olufemi Akitoye Ọgbeni J. Imokuede ati iyawo e, Ọgbeni G. A. Adewale ati iyawo re, ati awon Ọgbeni Fadina, Peters, J. G. Fatoan ati iyawo won ati ogbe- A. B. John.

Iyawo a towo b'osun o.

# Dokita Olumide Ko Lejo Mo

Ejo Kotemilorun ti awon Olopa nfe ba Dokita Oluyinka Olumide se nitori dida ti adajo da sile ninu esun pe o seru iwe ogun ati awon meji ni Kotu kekere ni a gbo pe Oyinbo Ọga Agba awon Ọlopa kowe wipe awon ko se mo.
Dokita Olumide ko l'ejo mo o

# Dokita Fihan Wipe

## Ọse Palmolive Le Jeki Oju Re Dara

LARIN ỌJỌ MERINLA



**Ara mi Jolo o tun Jide Nisisiyi ti mo tele ilana**

**Palmolive**




Iba ohun ti iwo yio se niyi :-
1 Fi ose Palmolive we oju 2 Fi biho re pa oju fun iseju kan 3 Fi aso nu kuro se be nigba meta lojumo fun ojo merinla.

EPO ILE AFRIKA

NI A FI SE ỌSE YI

COLGATE PALMOLIVE SOAP

## Ipade To Pa Bambari

AGEGE— Awon Egbe Agbe Ajimosepo ti Naijiria se ipade won ti ososu ni ojo kini osu September yi, ni Agege. Ogbeni Alex O. Williams ti ise Alakoso egbe ni o se Alaga ipade na, o si fi adura si ipade. Alaga so ninu oro re wipe opolopo eka egbe yi ti o wa ni awon ilu miran gbogbo ni nwon ti Rejista ti nwon si ti gba Iwe-eri (Certificate) eyiti o fi won han gegebi egbe Ajumosepo gidi, nitorina o ni ki gbogbo omo egbe se agiri lati da owo Ifilele (pay their share Capital) won ki osu October to pari.

Ogbeni S. C. Shodijo ni o soro tele Alaga, o so wipe o je ohun abuku ati itiju pupo wipe eka Egbe ti Agege ti o ti je olori ati ologiri pataki ni o tun njo r'ehin ninu Egbe Agbe Ajumosepo, nitorina ki gbogbo omo-egbe se giri lati da owo Ifitele won ki nwon le gba Iwe-eri laipe.

Ogbeni Elijah Enitan to wa lati Ijoko ni o bere wipe ki l'ese ti ipade ko fi kun bi ti atehinwa ? Alaga si fun lesi wipe awon ko fe opo enia lasan ti ko ni kan se, ti yio ma se esekan ile ese kan ode, eto egbe ti isisiyi ko gba oleraye enia laye, ayafi eniti yio ba sise fun ilosiwaju ati anfani gbogbo egbe.

Ogbeni F. Beckley da ni imoran wipe owo ponwun mejila sile meta ati sisi (£12:3:6d) ti a da ni ipade na ki a lo toju re si ile owo enia dudu (National Bank) Agege. gbogbo ipade si gba be Lehinti opolopo omo egbe ti soro tan, Ogbeni S.C. Shodijo fi adura kukuru mu ipade na wa si ipari.

O ye ki a daruko die ninu awon to wa si ipade na, awon enibi;- Ogbeni Alex. O Williams (Alakoso Egbe) M.F. Beckley (Igbakeji Alakoso Egbe) G.T. Ajibode (Akapo owo Egbe) S C. Shodijo (akowe owo Egbe) T.O. Mobolade. Johnson Agbede, Elijah Enitan. M. Adeyele F Babajide ati awon ti aye ko gba lati daruko tan.

A fi ipade miran si ojo kedogun osu yi.


# Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

**LOSAN ATI LORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE**

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.



Sodium N-Lauroyl Sarcosinate

SAME RAMILIAR, PACKAGE




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.



**OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.**

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun ehin te, nwon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyi ti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.

## O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Enia Baje.



## Always Read And Advertise In Eleti - Ofe.

## IRORA ORIKERIKE
### H ma so ni di Alara gigan tabi Aro



Nigbati Kidirin tabi Ọlọ inu rẹ ko ba ṣiṣẹ rẹ to o yẹ ki aran lọwọ. Bi bẹkọ iwọ papa yio mọ funra rẹ pe ewu mi'ọ. Ninu awọn ewu na ti irora orikerike jẹ ọkan o le jẹ wipe ọlọ-inu rẹ ko ṣiṣẹ rẹ to nipa aiṣe ẹjẹ rẹ.

Egbogi DE WITT yi a se nipataki lati jẹki Ọlọ inu rẹ berẹ si ṣiṣẹ rẹ iranlọwọ ti yio ṣe fun Kidirin ni lati kokọ wo gbogbo irora orikerike na fuye, Gbogbo awọn ẹjẹ ti ko sunwọn ti o mbẹ nibẹ yio kuro. Ọpọlọpọ iwe ni a ti nrba kakiri a yẹ ti, awọn enia ti dupẹ fun wa latari egbogi DE WITT'S yi ti nwọn si ri alafia ara wọn gba Boya iru egbogi yi le ṣe rere fun ọ si dan wo fun iyonu tirẹ lobere ni ṣobu egbogi Egbogi DE WITT,S yi a so ni pataki fun:-



ARUN ARUNGUN WODIWODI ẸHIN DIDUN. IRORA ORIKERIKE LAKUREGBE, ati gbogbo IRORA

Ohun ti o dawa loju ni wipe egbogi DE WITT'S jẹ eyiti a ṣe tonitoni gbogbo ohun elo rẹ lo si mọ gara.

**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**


## Ọkan Tunde Agogo Adesina

IBADAN— Irohin ti a tun gbo ni wipe nwon oku omokunrin kan ti oruko re nje Simpson Ajamu a r a ilu Ilorin ni okunrin na ti ojo ori re koju ogbon odun lo

N/gbati nwon ri oku na nwon ti ge ori re k u r o lara, nwon si gbe lo si odo awon olopa ijoba lehina ni nwon gbe lo fun ayewo Dokita ninu ile I w o s a n ti Adeoyo ni Ibadan.

A gbo wipe ibiti nwon ti ri oku okunrin na ko ju won buso kan abo lo si Ibadan ati pe leba irin Oko-ile (Railway track) ni nwon ti ri oku na o fere dabi ti akorin olohunyo Njemanze ti nwon ri oku re l e b a irin oko ile ni iyana Suru-Lere l'oke Ebute-Metta,


## KERE O !

OGBOMOSHO DUN ALMANAC 1956.

Yio jade fun tita ninu Osu October 1955 yi. Awon Aworan to wa ninu Almanac na niwonyi :-

Ołola Awolowo, Ołola S. L. Akintola, Oba Ejigbo, E. A. Ande (Jos) J. A. Adekola, M. A. Ladapo, Egbe Oba-bi-Oorun-kosi, Bibiani G. C. Ołola S. O. Ogundipe, Alaga Council Ogbomosho, Ajadi Onilu Ilorin, A. B. Awolola ati awon opo Aworan miran ti a kole ko tan.

Tete fi owo tire ranse ki o to tan. Eyo kan 1/-3d, Mejila 13/- Postage 6d.

J. A. ARE - EGBE, P. O. Box 7, Ilorin.


# Olu Epe Di Araba



## TI APA OMODE KOKA

Gegebi a ti so sinu Iwe Irohin wa Eleti-Ọfe yi ti ojo kerindinlogun osu July 1955, oro na ti bo aso lori nigisiyi fun enikeni ri gedegbe wipe Ọba Alaiyeluwa Olu Epe ti di Araba ti apa Omode koka.

Olu Epe ni yio se Alakoso Ile Igbimo Ibile (President) ti ilu Epe ti nwon yio si ipade akoko awon Olugbimo ni ojo Monday otunla, on si ni yio je ogunna gbongbo ti o ndato l'enu Igbin ninu ile Igbimo na, nitoripe ohun ti o ba se ni abe ge, ti ko si atako nibe.

Ki Ade pe lori, ki Bata pe l'ese o. Olorun Olodumare yio se olutos'ona ero yin ninu Igbimo na l'agbara Ọjise-nla.

Fatiha !

**ENJOY YOUR OWN SONGS**



SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING ON TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS NOW OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA

*S. O. OJO DI OLOGBE*

Ogbeni Samuel Oladiran Ojo, Akowe Western Regional Production Development Board pade jamba ninu ayokele re ni titi Agbeni ni Tuesday to si ja si iku ni Satide to koja. O le ni egbaji enia, ni awon Olotu Ile, alufa Ijo, Adajo, Agbejoro, Onisegun, Oga Ile Ise Ijoba, ati awon Saraki ilu lo pese nibi isin igbehin ti a se fun ni Ijo Baptist, Idi-ikan ni Monday to koja. Alaisi yi je omo oloye Ojo Ibadan ti Oje, o si je aburo ogbeni S. Ade. Ojo eniti o sese simi kuro ninu ise akowe Ile Igbimo Ijoba ile Nigeria.

Oluwa ko tu awon enia re ninu, ki Olorun gbe si afefe rere.

*OGBENI GRAIG DI OTUNBADE IGBORE*

Laipe yi ni a fi alagba J. O. Ade. Craig, adahunse, Oke Bola ni Ibadan, je oye Otunbade Igbore, Abeokuta. Lati ilu Ibadan de Eko ni ero ti wa se iyesi fun Oloye yi, o si ye pupo. Oye a mo ori o.

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos

**ARADAN NERVIGORA**

Ogun ele pataki fun imarale agba ati areme pipe fun awon alaya pupo. O dara fun inarun, eje dudu, isokun eju, ebigbon owo, ailesun, ailokun n'nu, ati isu fe arun bawonni. O je ajidewe fun awon ti agbara won ndinku. On na gun ni okunrin yi le ti o fi di "Afere kun bi ojo" 5/-6d pere ni pelu owo oko 1/-6d. c. g. 7/-Post Free.



**The Egba Trading Aradan Stores**

144, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P. O. Box, 2, Ebute Metta. Phone 44153
atun wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan.

BERE FUN **"AEROXON"**




OJULOWO EGBOGI Fun Esinsin, Yonmuyonmu, Kotonkan, Afopina ati fun Orisirisi Kokoro oniye ti o ba nje tabi ti o ba nta enia ni ara pelu. Oran Egbogi yi dara a si ma fa awon Kokoro wonyi lati wa to o wo. Bi nwon ba si ti ba le won koni le lo kuro lara re mo rara ni.

Price 6d Dozen 5/- Postage 1/6

Eyo Mejila tabi Jubelo ni ale fi ranse si Idale tabi si Ilu Okere rere o.

BERE MI SOBU:-

**WTERLOO MEDICINE STORES**

21, Obun Eko Street, P.O. Box 333,
Lagos, Nigeria.

WESTER REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

**VACANCY FOR STORES ASISTANT**

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Stores Assistant in the Stores Section of the Board Salary will be in the scale £126 x 6 - 132 x 12 - 180 per annum; point of entry depending on qualifications and experience.

**QUALIFICATIONS**

Applicants must be thoroughly conversant with Store rules and procedure in respect of vehicle spare parts and engineering equipment. Preference will be given to applicants who understand protective treatment methods and are able to select Bedford, Land Rovers and Ferguson vehicles spare parts.

Applications accompanied by copies certificates and at least two recent testimonials should be addressed to:-

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board,
Secretariat, Ibadan

to reach him not later than 30th September, 1955. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

**VACANCY FOR SENIOR STORES ASSISTANT**

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Senior Stores Assistant in the Stores Section of the Board. Salary will be in the scale £318 x 18 - £390 per annum, entry point depending on qualifications and experience.

QUALIFICATIONS: Applicants must be fully conversant with Store rules and precodure. Preference will be given to candidates who possesses a thorough knowledge of vehicle spare parts in respect of at least one of the following: Bedford, Land Rovers, Ferguson Tractors and Trailers.

DUTIES:

The selected candidate will be required to undertake, in addition to general store keeping, duties connected with the safe custody of all Board's vehicle spare parts. He will be responsible for the selection vehicle spare parts and engineering equipment and will be required to enter into a Bond with the Board.

Applications accompanied by copies of certificates and two recent testimonials together with names of Bondsmen should be addressed to:

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board,
Secretariat, Ibadan.

to reach him not later than 30th September, 1955. Only application of those selected for interview will be acknowledged.

Printed & Published by The ... Printing and Publishing Company, ... Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23570